**Ijọ́ Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu**
**Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nàìjíríà**
**ÌSÌN OMI MÁNNÀ**
**Kókó Àdúrà – ÌWÒSÀN PÍPÉ (6)**

**Ìjẹ́wọ́: Jeremíàh 32:17:** Á! Olúwa Ọlọ́run! wò ó, Ìwọ tí O dá ọ̀run òn ayé nípa agbára nlá Rẹ̀ àti nína apá Rẹ: kò sí ohunkóhun tí ó ṣòro fún Ọ.

**Orin Ìyìn àti Ìjọ́sìn**

1. Bàbá, gẹ́gẹ́ bí ó ti rí fún Námánì, rì mí sínú ibú ẹ̀jẹ̀ Jésù, kí O sì wòmísàn kúrò nínú àìsànkáísàn, ní orúkọ Jésù.
2. Mo pàṣẹ wí pé, ní ojoojúmọ́, ayọ̀ Olúwa yóò máa jẹ́ okun mi, ní orúkọ Jésù.
3. Àwọn àlúfà búburú, tí wọ́n n fi ayànmọ́ mi ré láti orí pẹpẹ òkùnkùn, ẹ kú nípa iná, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo ogun tí ó lòdì sí ètò ìṣúná mi, tapadà, ní orúkọ Jésù.
5. Ẹ̀jẹ̀ àti omi nínú àgọ́-ara mi, kọ àrùn gbẹ̀mígbẹ̀mí, ní orúkọ Jésù.
6. Ara, ọkàn àti ẹ̀mí mi, kọ onírúurú ìbọ̀dè ìyówù, ní orúkọ Jésù.
7. Bàbá mi, jẹ́ kí ẹ̀jẹ̀ Jésù dúró sáarín èmi àti àìsàn ìyówù tí ó n gbìyànjú láti wọlé sínú àgọ́-ara mi, ní orúkọ Jésù.
8. Mo sọ̀rọ̀ ìparun sí gbòngbò ìpọ́njú tí àwọn agbára àjẹ́ gbìn sínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
9. Gbogbo ọfà àìsàn tí wọ́n rán láti pa mí, padà sọ́dọ̀ ẹni tí ó rán ọ, ní orúkọ Jésù.
10. Gbogbo gbòngbò àti irúgbìn ìpọ́njú nínú àgọ́-ara mi, gba ifàtu nípa iná, ní orúkọ Jésù.
11. Mo de gbogbo ẹ̀mí àmúbọ́ lórí ayé mi, ní orúkọ Jésù.

12. Ẹ̀jẹ̀ Jésù, ṣe iṣẹ́-ìránṣẹ́ ìjákulẹ̀ sórí iṣẹ́ búburú gbogbo nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
13. Ẹ̀jẹ̀ Jésù, sọ gbogbo iṣẹ́ búburú nínú ayé mi d'òfo, ní orúkọ Jésù.
14. Ìwọ ọ̀tá àwọn ohunrere nínú ayé mi, gba ìparun, ní orúkọ Jésù.
15. Mo de ibùgbé agbára àìsàn ìyówù nínú ayé mi nípa ṣẹ̀ ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
16. Gbogbo ẹ̀mí búburú tó n ṣiṣẹ́ lòdì sí ìwàláàyè mi, ṣubú lulẹ̀ kú, ní orúkọ Jésù.
17. Mo di ẹ̀jẹ̀ Jésù mú lòdì sí ẹ̀mí ìkùnà ní bèbè àlàjá, ní orúkọ Jésù.
18. Mo di ẹ̀jẹ̀ Jésù mú lòdì sí ẹ̀mí ìdárungún sójúkan ní agbègbè ayé mi ìyówù, ní orúkọ Jésù.
19. Gbogbo ìdádúró òkùnkùn nípa àwọn alàjá tí mò n retí, kú, ní orúkọ Jésù.
20. Mo di ẹ̀jẹ̀ Jésù mú lòdì sí ìkùnà ní bèbè àṣeyọrí, ní orúkọ Jésù.
21. Gbogbo ààmì àìní-àwọn-olùrànlọ́wọ́ rere nínú ìran ìdílé mi, kú, ní orúkọ Jésù.